**Akiyesi**

Iwe Irohin Imọlẹ oju ewe mejila yio jade ni Ọsẹ ti mbọ. Sọ fun awọn ọrẹ rẹ ki e si tete rańṣẹ fun ti nyin nisisiyi.

Kọbọ meji pere ni.

OLOTU

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**FUN TITA**

Iwe Itan Igbeyawo Ọọṣa ati Ifọọtiọ ati bi Ọọṣa ṣe ntan imọlẹ rẹ sori aiye. Oyemọmọ ni 5/- fun ẹyọkan ati Iwe Adura Akanse ati Apẹrẹ ile Aiye 2/6d. Iwe itumọ ala ati ọna ti a fi owadi nkan pẹlu odu ifa. 5/-

Kọwe si:-

*Lawrence Bamgboye*
28, Upper Offin Lane,
Lagos.

VOL. VI No. 356 MONDAY NOVEMBER 12 – NOVEMBER 18 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# IJỌBA MBA AWOLỌWỌ Ṣ'ẸJỌ

**EKO:- Gbogbo ile ẹjọ lo kun sọsọ, ti inu ati ode ko si gbẹsẹ fun awọn ogunlọgọ enia ti nwọn wa si kotu nigbati awọn Ọlọpa mu Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre, ati Olori Ẹgbẹ Alatako ninu Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria ati awọn enia mẹrindinlọgbọn pẹlu rẹ wa siwaju Adajọ agba Ọgbẹni Showẹmimọ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi fun ẹsun pe, nwọn fẹ ba Ijọba ja'gun nigba kan.**

Nigbati awọn enia na de iwaju Adajọ, Agbẹjọro Ijọba ni awọn ko fẹ gbọ ọrọ kankan lẹnu wọn ni ọjọ na nitoripe, o tun ku awọn enia mẹta lẹhin, ti nwọn ti sa kuro ni ilu nisisiyi. Awọn Ọlọpa ko gba iduro Oloye Awolọwọ ati awọn yoku rẹ, nwọn ni ki nwọn mu wọn lọ si ọgba ẹwọn.



*Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ*

Loni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ yio tun farahan niwaju Adajọ l'Eko.

## OLOYE DAVIES ATI ỌDẸSANYA FẸ KI AWOLỌWỌ PADA SI'LE

Ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejọ oṣu yi ni Oloye H. O. Davies ati Ọdẹsanya pẹlu awọn lọọya Agbẹjọro miran ṣe iwe ibura si kotu wipe, awọn enia mẹtadinlọgbọn ti awọn Ọlọpa ko pamọ si itimọle ọgba ẹwọn, ti nwọn si kọ lati gba iduro wọn, ṣe ibura ni kotu wipe, awọn ni awọn idi pataki mọkanlelogun lati fi han Adajọ pe, awọn ni lati gba iduro fun awọn enia wọnyi ki olukuluku wọn si ni anfani lati wa ninu ile wọn titi ti ẹjọ na yio fi pari.



*Oloye H. O. Davies*

## OLOYE COKER KỌWE SI AWOLỌWỌ

Oloye G. B. A. Coker, ti iṣe Alaga Igbimọ Oluwadi awọn Ileṣẹ mẹfa ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ti da duro lẹnu iṣẹ nisisiyi ti kọwe si Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ wipe, awọn yio lọ si inu ọgba ẹwọn nibiti Ijọba fi Awolọwọ pamọ si lati gbọ ọrọ lẹnu rẹ ninu ohun ti on nṣe iwadi le lori.

## AWOLỌWỌ YỌWỌ YỌ'ṢẸ NINU ỌRỌ NA

Lẹsẹkẹsẹ ti iwe na tẹ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ lọwọ, ni o ti dẹti pada lafarahgba wipe, on ko ni sọ ohun kan ninu ọrọ na, nitoripe, Alakoso Ijọba Pajawiri ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, ti iṣe aṣoju Apapọ Ijọba ti fi oniruru ohun idiwọ si oju ọna fun on lati sọ on di ẹni ilẹ patapata ati ki ẹgbẹ on ti iṣe ẹgbẹ Afẹnifẹre le parẹ. Oloye Awolọwọ tun sọ siwaju si i wipe, ọkan ninu anfani ti Alakoso Ijọba Pajawiri na ko fun on ni wipe on ko, ri anfani lati ma a bi awọn ti nwọn nrojọ lẹra ohun ti nwọn nsọ niwaju Oluwadi na gẹgẹbi awọn miran ti ni anfani na.

Bi nwọn ba ti pari ẹjọ na, si ẹ o tun ma a gbọ ninu Iwe Irohin Imọlẹ wa.



*ỌGBẸNI SHOWẸMIMỌ*
*Adajọ Agba*



*Ọgbẹni Ọdẹsanya*

## Ọkunrin kan jomako sinu ile

**AUCHI:-** Bi enia jẹ ori ahun a ke, nigbati nwọn ngbe oku ọdọmọde kunrin kan jade ninu iyara rẹ, ti ina si ti yangbẹ

*Wo oju ewe kejọ*

## Ọkunrin kan pe oku-Ọrun l'ẹjọ

**ABA:-** Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni ọkunrin kan wa si kotu kekere Aba, ti o si sọ wipe, on pe Robert Mosis Ike lẹjọ nitoripe o jẹ on ni gbese pọnun mẹtadinlogoji owo ile ti o wa ni Clifford Street, Aba.

Ọkunrin na tun ṣe alaye fun adajọ wipe, lati ọdun 1957 titi di ọdun yi (1962) Robert ko ti san epinni ninu owo ile na fun on.

*Wo oju iwe kejọ*

# Apapọ Igbimọ Kerubu ati Serafu ṣe Idupẹ

IGBARA-ODO:- Irohin ko to amojuba ni eyẹ ipade ti awọn Apapọ Igbimọ Ijọ Mimọ Kerubu ati Serafu ṣe ni Igbara-Odo ni ọjọ Abamẹta, ti iṣe ọjọ ketadinlogbọn oṣu kẹwa ọdun yi titi di ọjọ kọkandilọgbọn oṣu na. Ipade na bẹrẹ ni agogo m ẹ j i l a ọsan pẹlu orin. Alaga I p a d ẹ na ni Alufa Agba H. E. Shadrak lẹhin adura, o ki gbogbo ipade na, o si gba w ọ n ni iyanju lati inu ọrọ Ọlọrun, Johannu 17 : 17-18. O si gba ipade na ni iyanju gẹgẹbi ọrọ Ọlọrun yio ti ṣe ma a gbilẹ siwaju larin Ijọ Enia-Ọlọrun, o si sọ nipa awọn E n i - Ọ w ọ Joseph Awosanmi (Ajamapo Ifẹ) Josaiah Araloyin (Ifẹ) ati James Ọmọsọpẹ Bamosun (Ile Shonka A r ẹ m ọ Ifẹ) ti nwọn yapa k u r o ninu Apapọ Ijọ Mimọ Kerubu ati Serafu. Awọn Igbimọ na si pinnu pe awọn ti o yapa na ko gbọdọ tun lo orukọ Ijọ Mimọ (United Church of Kerubu and Serafu Organisation) mọ.

Awọn Eni-Ọwọ ti o wa si Ipade na ni Alufa-agba H. E. Shadrak, Alufa-agba David Ojo ati Alufa-agba J. O. Falope (Ekiti) Alufa-agba J. A. Adesinyan (Ifẹ) Alufa J. A. Adesikun (Ifẹ) Alufa G. Ọmọtọsọ (Ikẹre Ekiti) Alufa Apostle B. O. Ọlọniyọ (Eko) Alufa S. B. Eniọla K i n g (Ado Ekiti) A l u f a Kọlawọle Igbara-Odo) Alufa M. Ajayi Walẹọla (Ẹfọn Alaye) Alufa S. A. Akinsọyinu (Igbara-Oke) Woli Jacob Adelana (Ifẹ) Woli Afuyẹ (Ikẹrẹ Ekiti) Woli E. Banji (I f ẹ) Woli E. Adeluwoye (Ọwọ) Iyaafin G r a c e Ọdẹku (Ado Ekiti) Alufa G. Ayagbure (Utẹ via Ọwọ) Alagba H T. Domingo Akọwe agba ati Alagba Alebru Akọwe agba (Eko)

Ọpọlọpọ ni a w ọ n enia nlanla ti o wa lati Igbẹdẹ Aiyetoro via K a b b a ati kakiri awọn ilu Ipinle Iwọ-Orun gbogbo. Ipade na si gbadura, pataki fun alafia Iwọ-Orun Naijiria.

# Oluwa ma fi aṣiri mi le aiye lọwọ, yẹyẹ laiye mọ

Mo ki gbogbo ẹ n y i n Olugbọ ọrọ mi. Oluwa ko ni fi aṣiri wa le aiye lọwọ o, Amin o, nitorina ẹ maṣe gbẹkẹle enia, nitori ti ara wọn ni nwọn nlepa, gbogbo enia lo dẹke aiye daiye agula, mo fẹ sọ fun ẹnyin Onigbagbọ pe ẹ ma jẹ ka tan ara wa jẹ, ko si igbagbọ mọ wahala lo kun nibẹ Baba nsare ọmọ lati fi ṣẹyọ ọmọ nsare baba lati fi ṣe owo, gbogbo ẹnyin e n i a mo fẹ ki ẹ mọ wipe ọpọlọpọ ninu awọn Onigbagbọ lo tun mba wọn ṣe lọji tabi alawo opa, mo fẹ ki ẹ mọ pe were ni awọn wọnyi Afọju si ni wọn pẹlu, ọpọ ninu awọn Bisọbu ati Woli ati Alhaji lo tun mba wọn ṣe ẹgbẹ buruku yi, mo fẹ ki ẹ lọ mọ pe ẹgbẹ ni fun yin, nitori ẹnyin nṣe ẹgbẹ ti ko ni anu, iwa yin ati abosi yin ni yio tu nyin ka, ohun ni Oluwa agbara ati ilu odi mi, abo mi ni ọjọ iponju, awọn orilẹ ede yio tọ ọ wa, lati ipẹkun aiye nwọn o si wipe lotọ, awọn baba yin ti jogun eke, ohun asan, iranlọwọ ko si ninu wọn, enia le ma da Ọlọrun fun ara rẹ? nitori awọn wọnyi ki ṣe Ọlọrun, JEREMIAH, 16, ESẸ 19.



Woli Kogberegbe

Gbogbo wọn gbẹkẹle ohun asan, nwọn si nyọ ninu ẹṣẹ wọn si nsare pẹlu, gbogbo wọn si bẹrẹ si yokun, nwọn n l o y u n ẹṣẹ nwọn si bi iparun, nitorina gbogbo ẹnyin Onigbagbọ ti ẹ nṣe ẹgbẹ Lọji ọṣi ati ibanujẹ ati iparun ni yio gbẹhin yin.

# ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ipade gbogbo Ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye yio tun wa ni ọjọ Abamẹta ti ṣe ọjọ kini oṣu kejila ọdun yi ni agogo m ẹ t a abọ ọsan (3 : 30 p. m.) ni nọmba 16, Bamgbose Street, Lagos.

A nfẹ ki gbogbo ọmọ Ẹgbẹ pe'sẹ si ibi i p a d e pataki na lati gbọ eto pataki ti a fẹ ṣe fun ọdun titun, bakanna ni ao pin Calendar Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye fun ọdun titun (1963) ti mbọ fun gbogbo a w ọ n ọmọ ẹgbẹ ati wipe, ao ṣe ikede ọjọ ti a fẹ ṣe ajọdun Ẹgbẹ. Nitorina, ki olukaluku ninu ọmọ Ẹgbẹ maṣe alaikowa si ibi ipade yi.

**Lateef Babalọla**
*Akọwe Gbogbogbo-ọ*


## Akiyesi Pataki




SENGOVAN TABLETS:- Jẹ ajidewe ẹgbogi fun awọn agbalagba ati ilera ati gẹgẹbi Ọmọkunrin.

SENGOVAN:- Jẹ ọkan pataki ti a ṣe iwadi ni ilu Okere ni ilẹ Jamani lọwọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn Onisegun Arẹmọ ti ilu Western Jamani fun arẹ ara eyiti ojo ori rẹ to Ogoji si Ogorin ọdun (40-80years).




SENGOVAN:- Jẹ ẹgbogi ti o ti wa lọjọ pipẹ fun anfani awọn agbalagba ilu Jamani ki a to ṣe amuwa rẹ si ilu Naijiria Ajẹbidan ni ogun yi.

**Irohin ko to afojuba**

*Bere:-* A o ri lọwọ awọn Onisegun Adugbo rẹ
Asoju:- Hassan Commercial Medicine Stores
26, Bishop Street Lagos.
Phone: 23745 Lagos.



## TANI FẸ KỌ ILE SI ILU-EKO ?

EMI FẸ BẸ Ẹ

Awa mba enia ra ILẸ ati ILE, iṣẹ wa si ni lati ba nyin kọ ILE nyin si ILU-EKO ati agbegbe EKO
Eyi jẹ "PEN-SAN" t Olodumare fun ẹ, ati fun Emi na pẹlu.

*ỌJỌ AYỌ NA DE!*

A ki gbe okere mọ didun ọbẹ, Ile labọ isimi oko.
ERE WA NIBẸ, Ẹ MAṢE JAFARA O!
ORẸ WA ARAKUNRIN ati ARABINRIN

*Ẹ fẹ ra ILẸ tabi lati ILẸ lati fi kọ ILE si ILU-EKO?*

Awa ti wa fun nyin, bakanna ni iranlọwọ wa fun nyin, fun ohunkohun t ẹ fẹ lati ra, bo jẹ ILE ati ILẸ ni, ao ba nyin ra wọn, bakanna ni ao ba nyin ra ILẸ ati ILE.

Afani nlanla ni fun awọn ti o ti ọ ILE ati ILẸ si ILU-EKO ati AGBEGBE RẸ

Eyi ni lati kede rẹ fun ẹnyin ti ẹ ti kọ I L E wipe:- **E. ADE-GBADEBO & SONS** mura tan lati ba nyin ma a gba owo ile nyin loṣoṣu laitaṣe.

Ẹ dan wa wo, ki ẹ wa wo bi awa tiri; ẹo yin Ọlọrun logo nipa iṣẹ tiwa.

*Ki ẹ fi Stamp Toro (3D) sinu Apo-iwe, fun dida esi Ibere nyin pada. Awa yio si tẹ nyin lọrun pẹlu ogo ti Oluwa.*

**The Manager**
PRINCE E. ADE. GBADEBO
29, Adesina Street, Odi-Olowo
Mushin-Lagos.

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

*Lati Ọwọ EJON'GBORO*

AWỌN IWE KOṢEMANI

Iwe Psalmu ati iṣẹgun ajẹ 2/6 Ẹyọkan. 24/- Dọsini kan. Iwe Adura lati bori gbogbo iṣoro 2/-6d Ẹyọkan, 24/- Dọsini kan. Iwe Itọnisọ Ala – 2/6 Ẹyọkan 24/- Dọsini kan.
Ko iwe bere awọn iwe miran ti o nfẹ. Fi owo ranṣẹ si:–

OLOTU,
P. O. BOX 236,
ẸBUTE MẸTTA, NIGERIA

### ASABA

Awọn Ẹgbẹ Ubulu Ohiti Co-porative ni ilu Ani ocha ni agbegbe Asaba, ti fun Iyaafin Agnes Ifeaki ni adọjọ pọnun (£150) nito tipe o ran ọmọ re lọ si ilu Oyinbo.

### INDIA

Rogbodiyan ija kan ti ṣẹlẹ larin Ijọba India ati Ijọba Chaina lori ẹnu aala ipinle awọn Ijọba mejẹji.

### ONIKAN

Ni ọjọ iṣẹgun ti ọjọ kẹfa oṣu yi ni dede agogo mẹfa irọlẹ ni nwọn ti oku Ọkunrin kan ẹni ọdun marundinlogoji ti o wọ ẹwu dudu kẹkẹre kan bata ati ibọsẹ lẹsẹ rẹ ti o nfo lori omi ni onikan.

Awọn ọlọpa ti gbe oku Ọkunrin na lọ si ile iwosan lakulaku l'Eko.

### YUGOSLAVIA

Enia metalelogun lo ku patapata ti enia metadinlogun si farapa gbogbe nigbati ọkọ Reluwe kan jasilẹ lati oju irin nigbati o nsare lọ.

### CONGO

Ọgbẹni Kasavubu ti i ṣe alakoso Ijọba Congo ti ṣe olin pajawiri si Ipinle Ila – Orun Congo nitori rogbodiyan kan ti o ṣẹlẹ ni ilu Leopilloville.

### NOWAY

Enia mejidilogun lo ku bamubamu ninu ijamba kan to ṣẹlẹ ninu ile iṣe awọn ti o nwa edu ninu ilẹ ni ọjọ aje ti iṣe ọjọ karun oṣu yi.

### EKO

Ifonijiṣi da bo gbogbo awọn ara adugbo Opopo Hawley l'Eko, nigbati ọkunrin kan, Bankọle Thompson ku si gbangba ode.

Awọn Ọlọpa si ti gbe oku rẹ lọ si ile iwosan lakulaku.

### AMERIKA

Ijọba Amerika ti tun dan Bombu Oloro kan wo larin ọsẹ ti o koja yi. Lati inu ọkọ ofurufu ni nwọn ti ju Bombu na silẹ. Eyi lo lagbara ju ninu Bombu merindelogbọn ti nwọn yio danwo.

### ILORIN

Ọgbẹni Cyril Okori ku lojukan na nigbati mọto ti o nwọ lati lọ fi oju ni ita Ajiari ni Ilorin kolu mọto awọn Ọlọpa ti o duro.

Awamọto na ko farapa.

### ILOGBO

Ijọba ti sọfin wipe, enikeni ko gbọdọ gbe ibọn kaakiri ilu agbegbe na fun oṣu mẹfa.

### APAPA

Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati Ọkunrin kan fe sokalẹ ninu ọkọ oju omi ti ese re seesi ye ti o si ko sinu Odo Oja. Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa de ṣogbọn nwọn ko ri oku Ọkunrin na di bi a ti nkọ iwe yi.

### EBUTE — METTA

Jinnijinni da bo gbogbo awọn Olugbe nọmba 44, Olokodana Street Ebute - Metta nigbati Ọkunrin kan Samuel Ayọdele, ẹni Ọgọta ọdun ku sinu iyara rẹ.

Awọn Ọlọpa ti gbe oku rẹ lọ si Lakulaku ile - iwosan Eko fun ayewo.

### ỌBALENDE

Awọn Ọlọpa ti mu Ọdaran kan John Eke, ti awọn Ọlọpa sọ wipe ko ni Ibugbe kan, fun ẹsun pe o wọ inu ile kan ni nọmba 66, Ajeniya Street Ọbalende ni dede agogo mejo o si ji ṣokoto kan ti iṣe ti Memudu Adigun. Nwọn ri ṣokoto na lọwọ rẹ, nwọn si ti i mọle.

# EYI NI ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

## ỌJỌ AJE NOVEMBER 12 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Ibẹrekodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Sagbẹ, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Remo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilarọ, Oja - Odan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ IṢẸGUN OCTOBER 13 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Obun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Epẹ |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo Oyedeji, Ogburo, Egbeda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe Ishan, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Epe, Iloba, Imuroko, Erinmọ, Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo - Aiyedun |

## ỌJỌ'RU NOVEMBER 14 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, Badagry |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodekẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Owa, Erunwọn Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ NOVEMBER 15 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Agege, Ikeja |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Oba, Kajọla, Ajegunle, Idọgọ |
| IBADAN | Aalupọn, Ajegunlẹ, Owode, Igbo-ọra |
| IJEBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Agoiwoye, Ijẹsha, Ijebu, Isara Imodi |
| IJESHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijebu,-Ijesha |
| EGBADO | Lasilọ, Idiemi |
| EKITI | Okemsi.e, Ilaki, |

## ỌJỌ ETI NOVEMBER 16 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Ibẹrekodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Sagbẹ Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Remo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagbà, Ilarọ, Oja—Odan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ ABAMẸTA NOVEMBER 17 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Obun - Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe Isara, Imodi, Ishan |
| IJẸSHA | Epe, Iloba, Imuroko, Erinmọ Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo—Aiyedun |

## ỌJỌ AIKU NOVEMBER 18 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodekẹ, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowo, Temidire |
| IJEBU | Ikẹnnẹ, Ọkun - Owa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AJE NOVEMBER 19 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikeja, Agege, Ebute-Ero, Ọjọ Ajido |
| EBLOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Oba, Kajọla, Ajegunle, Idọgọ |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Agoiwoye, Ijesha-Ijẹbu, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijebu-Ijesha |
| ẸGBADO | Lasilọ, Idiemi |
| EKITI | Okemesi, Ilaki |

